# IPỌNJU WA TI O FẸRẸ

**2 Kọrinti 4:17, 18; 5:1-20**

**ẸKỌ 396 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ninu gbogbo ipọnju wọn, oju a pọn ọ, angẹli iwaju rẹ̀ si gbà wọn" (Isaiah 63:9).**

## Iṣisẹ Rẹ̀

Ki ni ipọnju? Lotitọ ni pe bi iwọ ba wa ninu aisan, iwọ wà ninu ipọnju; ṣugbọn bi a ba n "sọrọ nipa rẹ," bi a ba ṣá ọ tì, bi awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni ile-iwe ba korira rẹ nitori ti iwọ jẹ́ Onigbagbọ, ipọnju ni eyi pẹlu.

Itumọ Kristiani, orukọ eyi ti a fi n pè wa, ni jijọ Kristi – gbigbe iru igbesi-aye ti Jesu gbé – eyi si n mú inunibini wá.

## Apẹẹrẹ ti Jesu

Nipa ẹkọ wa oni, bi a ba ṣe aṣaro nipa igbesi-ayé Jesu, yoo ràn wá lọwọ lati le ru "ipọnju wa ti o fẹrẹ" pẹlu ayọ̀, nitori bi o tilẹ jẹ pe ipa ọna ti o là silẹ niwaju Rẹ la ọna iṣoro ati ipọnju kọja, ti opin rẹ̀ si yọri si ikú lori Agbelebu, Jesu tẹjumọ Ọlọrun, ifẹ Ẹni ti o jẹ́ didùn inu Rẹ̀ lati muṣẹ, eyi si fun Un ni ayọ̀ lati le fara dà. (Heberu 12:2).

Idanwo kin-in-ni ti a mẹnu bà ninu Bibeli ni nigba ti a ti ọwọ Ẹmi Ọlọrun dari Rẹ̀ si aginju nibi ti eṣu ti dán An wò. Nibẹ ni o gbaawẹ fun ogoji ọsan ati ogoji oru. Nigba ti o rẹ̀ Ẹ ti ebi si n pa A, eṣu wá lati dán  An wò.

Bakan naa ni o ri pẹlu awa naa lọjọ oni: eṣu yoo wá lati dán iwọ ati emi wò nigba ti a jẹ alailagbara rara, nigba ti o rẹ̀ wá, nigba ti ebi n pa wá. Ṣugbọn apẹẹrẹ ti Jesu fi hàn wá bi awa ṣe le bori oludanwo, ki a si ni iṣẹgun.  Jesu fi ọrọ Bibeli dá eṣu lohun, eṣu si fi I silẹ. Iwọ le ri bi o ti ṣe ohun danindanin fun wa to lati maa kọ́ awọn ẹsẹ akọsori wa. Nigba ti oludanwo ba dé, nigba miiran bi kikún omi, ti o si n gbiyanju lati mu wa ṣe aigbọran si Ọlọrun, Ẹmi Oluwa yoo gbé ọpagun kan soke si i (Isaiah 59:19); ọpagun naa si ni Ọ̀rọ Ọlọrun.

Jesu mọ̀ pe awọn idanwo wọnyii ki i ṣe ohun ajeji. Gbogbo eniyan ni o maa n doju kọ, "ṣugbọn olododo li Ọlọrun, ẹniti ki yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn ti yio si ṣe ọna atiyọ pẹlu ninu idanwò na, ki ẹnyin ki o ba le gbà a" (1 Kọrinti 10:13).

## Ere Pupọ

Ni ọjọ kan nigba ti Jesu gun ori oke lọ, O pe awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ O si wi pe,  "Alabukún-fun li awọn ẹniti a ṣe inunibini si nitori ododo: nitori tiwọn ni ijọba ọrun. Alabukún-fun li ẹnyin, nigbati nwọn ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini si nyin, ti awọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi. Ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o si fò fun ayọ̀: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun: bẹ̃ni nwọn sá ṣe inunibini si awọn wolĩ ti o ti mbẹ ṣaju nyin: (Matteu 5:10-12).  Ni igba miiran O wi pe,  "Bi nwọn ba ti ṣe inunibini si mi, nwọn ó ṣe inunibini si nyin pẹlu" (Johannu 15:20).

Jesu mọ̀ pe idanwo ati ipọnju n duro de Oun, ṣugbọn sibẹ O ni inudidùn lati ṣe ifẹ Ọlọrun.

## Awọn Idanwo Jesu

Nigba ti Jesu wo awọn ẹlẹmi eṣu meji ara Gergesene sàn, awọn eniyan ilu naa bẹ̀ Ẹ pe ki O kuro ni ilu wọn.

Nigba ti O lé awọn ẹmi eṣu jade ti O wo awọn alaisan ati awọn ti ara n ni sàn, awọn Farisi sùn Un lẹsùn pe O wà ni irẹpọ pẹlu ẹmi eṣu – O n lé ẹmi eṣu jade nipa Beelsebubu, olori awọn ẹmi eṣu.

Nigba ti ebi n pa awọn ọmọ-ẹyin Jesu ti wọn si n ya ipẹ́ ọkà ni Ọjọ-isinmi, ati nigba ti Jesu wo ọkunrin ti ọwọ rẹ̀ rọ sàn ni Ọjọ isinmi, awọn Farisi n kùn pe Jesu kò pa ofin Ọlọrun mọ́ nipa Ọjọ isinmi.

Wọn wá ọna lati fi ọ̀rọ Rẹ̀ dẹkun mu Un, ki wọn ba le wá si I lẹsẹ. Awọn Farisi, awọn olori alufaa ati awọn agbaagba n jowu nitori Jesu n ṣe ọpọ iṣẹ iyanu, ogunlọgọ ninu awọn eniyan ti a kò naani si n tọ Ọ lẹyin. Nikẹyin awọn eniyan wọnyii kan naa ni o mú ki a kan Jesu mọ́ agbelebu.

Jesu fara da gbogbo rẹ̀, ani ikú ori agbelebu, O fara da itiju nitori O n wo ayọ̀ ti o n duro de Oun nigba ti O ba ti pari iṣẹ ti Ọlọrun ran An lati ṣe.

**Apẹẹrẹ ti Paulu**

Paulu paapaa mọ̀ pe idanwo ati ipọnju n duro de oun nitori ti Oluwa ti wi pe "Emi o fi gbogbo iya ti kò le ṣaijẹ nitori orukọ mi han a." Paulu n yọ̀ ninu ipokipo ti o wu ki o wà nitori ti ó mọ̀ pe nigba ti oun wà ninu ipọnju, Jesu n ṣe olutọ oun. Jesu mọ bi o ti ri fun Paulu, nitori oun paapaa ti jiya ri. Bibeli sọ nipa awọn ọmọlẹyin Jesu ni akoko Isaiah pe "Ninu gbogbo ipọnju wọn oju a pọn ọ, angẹli iwaju rẹ̀ si gbà wọn."

Paulu sọ nipa "ipọnju ti o fẹrẹ."  Kò ka a si ohun ti o ṣoro ju lati fara da ọkọ rìrì, isọlokuta, lilù, ewu ninu ibú, ewu laaarin awọn eke arakunrin, ninu laalaa ati irora, ninu adura ati awẹ, otutu ati ihoho, ani ninu tubu pẹlu nitori ki oun ba le waasu Jesu fun awọn eniyan, nitori ti Ọlọrun yan an lati waasu, o si jẹ́ ayọ̀ Paulu lati ṣe ohun ti Ọlọrun fẹ ki oun ki o ṣe.

**Wiwu Ọlọrun**

A n ranti Jesu nigba ti idanwo ba de. Oun kò wá awọn ohun afẹ ayé yii. O dù lati ṣe ifẹ Baba Rẹ̀ ti ó wà ni Ọrun. Awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin miiran a maa dù lati tẹ́ ara wọn ati awọn ọrẹ wọn ayé lọrun. Awọn ọmọbinrin a maa gẹ irun wọn, wọn a maa fi atike tabi nnkan bawọnni pa oju wọn nitori ti awọn ọrẹ wọn n ṣe bẹẹ, awọn ọmọkunrin nigba miiran a maa dá irun gigun si, tabi ki wọn gé irun wọn lọna kan gẹgẹ bi aṣa ti o wa lode.

Bi wọn ba n pẹgan wa tabi ki wọn yọ wa lẹnu nitori ti awa ko ṣe awọn nnkan wọnni ti awọn olufẹ ayé n ṣe, ranti pe a ti dán Jesu wò "li ọna gbogbo gẹgẹ bi awa, ṣugbọn lailẹ̀ṣẹ" (Heberu 4:15).  Oun mọ iru wahala ati inira ti ọdọmọkun ati ọdọmọbinrin maa n bá pade ni akoko idanwo, nisisiyii Oun si joko ni ọwọ ọtun Baba ni Ọrun, O si n bẹ Ọlọrun ki O le fun ọ ni iranwọ ati igboya nitori itoye Rẹ̀.

**Fun Ire Wa**

Njẹ kò ha n jẹ́ iyalẹnu fun ọ eredi rẹ̀ ti aisan fi n ṣe ọ ati ti idanwo kikoro fi n de ba ọ? Bi iwọ ba jẹ Onigbagbọ́, nitori pe Ọlọrun fẹran rẹ ni, O si n fẹ ki o jẹ́ mimọ́ gẹgẹ bi Oun pẹlu ti jẹ́ mimọ́. Ipọnju a maa kọ́ wa ni suuru. Wọn a maa kọ́ wa lati le ni ẹmi ibakẹdun fun ẹlomiran ti o wà ninu ipọnju. Wọn a maa sọ igbagbọ́ wa di lile. Nigba ti Jesu ba mu wa la idanwo kan já, eyi yoo fun wa ni igbagbọ pe oun yoo mu wa la omiran já. Idanwo a maa rán Onigbagbọ́ leti bi Jesu ti jiya to fun un.

Inu wa dùn lati mọ̀ pe Ọlọrun fẹ wa to bẹẹ ti O fi n bá wa wi.  A ko le jẹ ọmọ rere ninu ayé yii ayafi bi awọn obi wa ba n bá wa wi. Bakan naa ni a kò le jẹ Onigbagbọ́ rere bi ko ṣe pe Ọlọrun ba n bá wa wi.

**Itọwo Adùn Ọlọrun**

Paulu mọ pe bi oun tilẹ gbé ọgọrun ọdun laye, bi iṣẹju kan ni yoo jẹ bi a ba fi wé ayeraye – ti kò lopin –ti oun yoo si wà pẹlu Ọrẹ ati Olugbala oun. Ọlọrun ti fun un ni itọwo adùn Ọrun nigba ti a gbe e soke lọ si Paradise.  Ọlọrun a maa fun wa ni itọwo adun Ọrun ninu Ẹmi Rẹ̀ ti o n gbé inu ọkàn wa.

Nigba miiran Jesu a maa sún mọ́ wa pẹkipẹki, a si maa ṣọwọn fun wa to bẹẹ ti yoo fi dabi ẹni pe ki a fi ayé yii silẹ lati wà pẹlu Rẹ̀ ni Ọrun. Paulu paapaa ti ni lati ni iru ọkan bayii bi yoo ti maa fi oju sọna fun akoko naa ti oun yoo fi "ile rẹ̀ aye" yii silẹ lati wà ni ibugbe ni "ti o n ti Ọrun sọkalẹ wá."

**Idanwo Ikẹyin**

Ifẹ Paulu ni lati fi ayé yii silẹ lati wà pẹlu Oluwa ṣugbọn oun mọ̀ pe boya oun wà titi Jesu yoo fi dé tabi boya oun kú, o jẹ ọranyàn fun oun lati fi ọkàn otitọ sin Ọlọrun lojoojumọ.  Ni ọjọ kan oun yoo ni lati duro niwaju itẹ idajọ Kristi lati ṣe iṣiro igbesi-aye rẹ̀.

Olukuluku wa, a baa jẹ́ Onigbagbọ́ tabi ẹlẹṣẹ, ni yoo jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun, fun awọn ohun wọnni ti o ti ṣe ninu ayé yii.

Lojoojumọ ni a ni anfaani lati ṣe iṣẹ rere fun ọmọnikeji wa – lati bẹ ọrẹ wa ti o n ṣe aisàn wò, lati ṣe inu rere si aladugbo wa lati gbọran si baba ati iya wa lẹnu pẹlu ọkàn ti o kún fun ayọ̀ bi ẹni pe Jesu tikara Rẹ̀ ni o wi fun wa lati ṣe bẹẹ. Jesu sọ pe a o fun wa ni ere bi o tilẹ jẹ pe ago omi tutu ni a fun eniyan nitori Orukọ Rẹ̀. Ṣugbọn gbogbo nnkan wọnyii ni a gbọdọ ṣe bi ẹni pe fun Jesu bi a ba fẹ gba iyin fun wọn. Awọn ohun ti a ba ṣe lati gba iyin awọn eniyan ki yoo ni ere ni Ọrun.

Ẹ jẹ́ ki a kẹkọọ gidigidi gẹgẹ bi Paulu ti ṣe fun idanwo ikẹyin ti olukuluku wa yoo ṣe. Gẹgẹ bi a ti n kọ́ iwe fun idanwo wa ni ile iwe bakan naa ni a ṣe gbọdọ kọ́ iwe Ọlọrun ani Bibeli, ki a ba le mọ ifẹ Rẹ̀; awa si n gbadura bẹẹ pe ki o le ràn wá lọwọ ki a le maa fi awọn ohun ti a n kà ninu Ọrọ Rẹ̀ ṣe iwa hù lojoojumọ.

Ẹ jẹ ki a fi inudidun, nitori itoye Jesu, fi ara da "ipọnju wa ti o fẹrẹ" ti o n wá si ọna wa, ki a si ṣe awọn nnkan wọnni ti a mọ̀ ninu ọkàn wa pe Ọlọrun n fẹ ki a ṣe. "Nitoripe gbogbo wa kò le ṣaima fi ara hàn niwaju itẹ́ idajọ Kristi; ki olukuluku ki o le gbà nkan wọnni ti o ṣe ninu ara, gẹgẹ bi eyi ti o ti ṣe, ibã ṣe rere ibã ṣe buburu."

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni "ipọnju ti o fẹrẹ" ti Paulu n tọka si?
2. Bi a ba fi inu didun fi ara da awọn ipọnju wa gẹgẹ bi fun Jesu, ki ni yoo jẹ́ ere wa?
3. Ki ni "ile aye" yii ti Paulu n tọka si?
4. Ki ni Paulu n fẹ ki a fi wọ oun nigba ti ile rẹ̀ ayé yii bá wó?
5. Ki ni Ọlọrun n fi fun wa ti o n mu ibẹru ikú kuro?
6. Ki ni ṣe ti a fi n ṣiṣẹ ti a si n kẹkọọ ki a baa le yẹ ni ẹni itẹwọgba lọdọ Kristi?
7. Niwaju ki ni gbogbo wa yoo ti fi ara hàn ni ọjọ kan?
8. Ki ni a o gbà nigba ti a ba fi ara hàn niwaju itẹ Kristi?